# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL. I. NO 22. SATURDAY, DECEMBER 9, 1922. FOURPENCE

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### IYAWO DÙN L' ỌṢINGIN.

Olobo ta wa pe Ojiṣẹ-Ọlọrun JOHNNY ROBBIN WILLIAMS, ti Ijọ *Baptist* àgba npete ati gbe omidan VIRGINIA KẸKẸ, Ifa-nfanu ARCHDEACON ati Mrs. N. JOHNSON olõgbe, ni iyawo ni ọjọ kejila oṣù yi.

### IJỌ BROTHERHOOD NṢE BI ARÌRA.

Ijọ *Brotherhood* ti Eko npete ati ṣe Ìsin Isọji lati ọjọ kẹtadi-logun oṣu yi titi fi dé ọjọ Keresimesi, nigbati nwọn yio fi Ìsin Ikore pari rẹ̀.

Ki BABA m' ọjọ́ ró.

### OMI TITUN, ẸJA TITUN.

A gbọ́ pe Ìgbimọ Ijọba eyiti Gomina CLIFFORD Olu-ọla fi ẹe ọ̀rọ sọ ninu Ile-ajọ Ìgbimọ Ọba, ti ọjọ́ 29 oṣù *March* ti o kọja, yio di didá silẹ̀ ninu oṣù *January* ọdun t'o mbọ̀. Gẹgẹ bi o ti jẹ́ pe a yõda fun ilu Eko lati yan enia mẹta ti yio ṣoju rẹ̀ ninu Ìgbimọ titun yi, a ní ireti pe awọn ará ilu yio jí gìrí si iṣẹ ribiribi yi, nigbati asikò bá tó A ni ọ̀rọ tian-tian lati sọ si ohun yi, ti a ṣọ́kù di "ọjọ́ miran ọjọ́ rere."

### KANO ILE ÌGÁRÁ.

Ìhin pupọ̀ kan ni lati Kano wá fun iṣẹ-olè ti pupọ awọn Gambari nṣe nibẹ, a sọ pe bi ilẹ bá ti ṣu, o di ki olukuluku enia wà ninu ẹru-jẹ̀jẹ fun idagìrı awọn ọsọlẹ loru: ọpọlọpọ ile ni a gbọ́ pe awọn ma-so-ndoki

yi kó; a wipe nwọn nṣe iṣẹ jamba yi lai bikita, ti nwọn si nlọ̀ di onile mọ'le: ti ihin yi bá ri bẹ̀, a ké si Ijọba ki o má ṣài gba awọn enia ti o wà ninu ewu bayi ni ilu awọn "ọmọ-gba'ja-ibinu."

## ỌBA L' O T' EHIN ERIN FỌN!

Ẹniti o bá ka Iwe-irohin Ijọba ti ọjọ́ 23 oṣù ti o kọja yio ri i pe gbogbo owó-otitọ̀ takada, bi emi ni Iwe-yiyawó, Iwe-adehùn, "Ganrandi" ati awọn iwe bawọnni ni Ijọba bu owó si patapata. O si ti di ofin nisisiyi.

## GBA WÈRE NG O GBA WÈRE.

A tún ṣe eré Ijiyàn miran ni *Thursday* ọ̀sẹ yi ni Gbàngan *Grammar School*: ohun ti a fi ṣe ijiyàn ni pe "Eré ti awọn Ile-iwe Giga nṣe lemọ́lemọ́ nisisiyi ko "tọ suna."

ERIC O. MOORE, Amofin ati Ọlọla ati ọgbẹni S. A. FAWEHINMI ọkan ninu awọn olukọ ile-iwe na li o jọ tako ara wọn. Ile kún bìba

## Ẹ KÚ EWU ỌKỌ̀.

A ki Ẹni-ọ̀wọ M. S. COLE, "kábọ̀" lati Ilu-oyinbo ti o ti lọ lati oṣù karun sẹhìn: ọgbẹni nā bá ọkọ̀ *Abinsi* "ayarabi-aṣà" dé ni ọjọ́ *Wednesday* ọ̀sẹ ti o kọja.

## ỌRỌ ỌMỌ JÀ-NTÒ-JA-NTÒ!!!

A gbọ pe ni Ipade ti a ṣe fun fifi awọn ọmọ-ọwọ hàn (*Baby show*) ni Ile-iwe Ita Tinubu, ni *Wednesday* ọjọ 29 oṣù ti o kọja, nigbati a fi nṣe Ọsẹ-Ilera, ko si Abiamọ kan ti o gbé ọmọ rẹ̀ yọju.

## EYI NKỌ̀?

Bi ọgbẹni kan, akọwe ni Ile-ipin'we (*Post Office*) nibi, ti o njẹ́ WALTER LISK ti ṣẹ̀ṣẹ gba owó-oṣù ti o kọja owó na jẹ pọ́nwùn mejidi-logun (£18) ti o si fi si ibi kan nibi iṣẹ wọn, bẹ̀ni o fẹ̀kù: ki a má ṣẹ̀ṣẹ tún sọ ti idámú ti irú ọ̀fo ojiji bẹ le múwa, pẹlupẹlu ninu eyiti ara awọn ẹlomiran gbẹkan fun aisi owó ni'lu nisisiyi.

A bá ọgbẹni nā dárò.

## MAMMY RE 'LE O, ILE L'O LỌ KO ṢINA!!!

A bá *Bishop* HOWELLS, ati awọn ebi rẹ̀ kẹdùn ọ̀fọ ti o ṣẹ̀ wọn ni *Friday* ọ̀sẹ ti o kọja nipasẹ ikú iya *Bishop* nā, ti o ṣẹlẹ ni Abẹokuta.

K' OLUWA fi i s' afẹ́ẹ rere.

## "IJỌ IBILẸ̀ NṢE 'HUN ÀRA!!

## "ẸNI A PETE-PERO K' A S' ỌWỌ RẸ DE ILẸ, NI PELE LI O NPELE SI I."

O to akoko nisisiyi ti o yẹ ki awa enia dudu mọ daju pe "agbajọ ọwọ ni a nfi sọ aiya," ati pe bi a ba tu ọwọ ka, a o ṣubu, ki isi ṣe mimọ lasan nikan, ṣugbọn fifihan ninu iwa wa pẹlu. Mo ṣe ori rere l'ọsẹ t'o kọja, mo ri Iwe-ipe kan gba lati ọdọ akọwe "Idapọ ẹgbẹ akọrin Ijọ Ibilẹ" (*African Church Choir Union*) pe ki ng wa ba wọn wo iran ranpẹ kan ni *Benella Davies School-room* ni ọjọ kẹrin oṣu *November*, bi a ti fi ọwọ ṣere lori duru. Nko ka a si nkankan, mo fẹrẹ le wipe, kini iba wa nibẹ? Irohin ko to afojuba. Nigbati mo de ibẹ ipẹtẹ pa igba ni. O to ohun ti a le ko ara wa lọ si Ẹhingbẹti si; Aluduru Ijọ Bẹtẹl, ọgbẹni R. O. Taylor "A-f'ọwọ-yọ-lori duru" fi han wa bi a ti gba igi loju ti isọrọ ẹni rẹ. Ko to ya ko to ọfẹ, bi mo sanwo igbadun na ko le to bẹ, nigbati awọn omidan. olohun 'yọ t'ẹnu b'orin ti Wundia F. Olumide fẹrẹ f' orin jẹ k' a lala pe a wa ni *Paradise*, o dabi ẹniti ko ma dakẹ mọ. Wundia T. Ipinlaiye ati oluranlọwọ aluduru Bẹtẹl ọgbẹni A. Abọyade Cole wipe, ki ti ẹnikini lọ wa bi joko si nitori "ẹnikan ki jẹ awa de" ninu orin ajumọkọ enia meji wundia E. Oriade ni on gbe omiran de. Olubori gbogbo rẹ bi ẹṣin meji ba sure la le mọ ọkan t'o le ya, nigbati ọgbẹni Cole tun tẹnubọ orin ilẹ wa, o dabi ki a ma lọ mọ akọtunkọ ni, a si fi awo wo ti Baba ẹgbẹ yi (ẹni-ọwọ E. A. Akiọla, ti ṣajo silẹ fun wọn pari rẹ. A si ni anfani ati gbọ ninu ọrọ ti Baba ẹgbẹ yi sọ wipe, a da ẹgbẹ yi silẹ niwọn ọdun kẹrin sẹhin fun ire awọn ẹgbẹ akọrin ni gbogbo Ijọ enia dudu, ki irẹpọ le wa larin awọn aluduru ati akọrin ki a le tun orin ilẹ wa ṣeki a si ma fẹ lati fihan pe "tẹni ni tẹni akisa ile ina. Ẹgbẹ yi si wa

ni irẹpọ pẹlu idapọ Ijọ Ibilẹ. Eyi fihan wa pe Ijọ yi ko le ṣaima lọsiwaju, eyiti o jẹ pataki ni ki aiye le mọ wipe ibi gbogbo ni a nko adiẹ alẹ, ni ti orin ilẹ wa, "lọ si ariwa, lọ si Gusu, ile ni abọsimi oko."

A ko le ṣe alai ranti olore ẹni ; eyini ni Akikanju akọwe ẹgbẹ yi, ọgbeni Ayọ Ajala ọga ẹgbẹ akọrin ti Ijọ Jehovah Shalom (U. N. A.) ẹniti ko jẹ ki ng padanu iran yi, ti o si ṣe ayan ti eto idaraya yi fi lọ lẹsẹsẹ laisi abamọ. A ko le ṣe alai sọ fun awọn ẹgbẹ yi pe ipa ọna rere ni nwọn tọ ki olukuluku ma ranti pe ede ati iwa awọn baba wa ni ki a ma tẹle nipa ajumọṣe ti ki iṣe ajijaduṣe ki temi ṣa ma ba wọ inu rẹ. Oluwa kio ma ṣe iranwọ fun ẹgbẹ yi, kio si jẹ ki nwọn le ma tẹ siwaju o. Ki ire ilu wa ti nwọn nwa le ma gbilẹ lati isisiyi lọ ati titi lai. *Amin.*

Gẹgẹ bi a ti gbọ pe oṣu mẹta mẹta ni ao ma ṣe idaraya yi, a ni ireti pe ti oṣu mẹta ti o mbọ yio ni arẹnrẹn pupọ.

AGUNFAN.

---

## OPEN LETTERS No. 10.

To T. K. E. Phillips Esqre. A. T. C. L.
Organist,
Christ Church Pro-Cathedral.
Lagos.

Dear Sweet Singer,

The success which attended the rendering of the sacred Cantata "Daughter of Jairus" by your choir with the valued assistance of several Ladies and Gentlemen under your able management, in the evening of Wednesday last, at the Town Hall (Glover Memorial) is another evidence of your unsurpassed musical attainments: a bird has just whispered to me of your successfully passing the Inter Mus. Bach (Lond.) only recently ; for this you have my congratulations.

May I be permitted to suggest your taking in hand the composition of Native Airs, say during your spare moments, as an attempt such as this will not only tend to the further enhancement of the rich melody not unconnected with Yoruba hymnology, but will be a veritable boon to all lovers of Music in this direction : by the way, your famous dirge "Oluwa Awa ma de" composed on the occasion of a Memorial Service for the late Bishop Johnson in 1918, is still fresh in my mind.

More power to your elbow, old chap ! ! !

EKO AKETE.

## No. 11.

To J. Egerton Shyngle Esqre.
Barrister-at-Law
Leader, Nigerian Bar.
37, Broad Street, Lagos.

Dear Old Blackstone,

Have just been told of the exemplary part played by you the other evening, whilst discharging the duty of Chairman for the Play got up at the G.M. Hall under the auspices of the Bethel Church Choir, nor do I overlook the act of some of your distinguished Supporters, to wit, the redoubtable "H.M." "Ọmọtaku" Thompson, and others who gave cheerfully when that little girl—one of the *Dramatis Personæ*—was passing her flowers round the audience for sale.

Well Done, thou worthy scion of the Illustrious House of Laṣorè.

Eko Akete.

---

## ỌKAN KI GBÉ.

Ọkunrin kan wa, a ma jẹ oriki pe, "Ọkan ki gbe' bi o ba ti yọ lọkankan, ti o ba ki i pe, ọkan ki gbe on na a sọ pe, "eyiti iwọ na nṣe yẹn ko ni gbe o" O wa ku si ọwọ iwọ tikalarẹ lati mọ ohun ti o nṣe ti ko ni gbe, yala ire ni, yala ibi ni, o sa daju pe, ọkan ko ni gbe nibẹ.

Oriki ọkunrin yi dara pupọ loju mi ni temi, tabi o ti ri loju rẹ ? Sa ro o wo, ọkan ki gbe, oriki na ba ede Bibeli mu, "Eniti iṣe alaiṣotọ, ki o ma ṣe alaiṣotọ nṣo, ati ẹniti iṣe ẹlẹgbin, ki o ma ṣe ẹlẹgbin nṣo, ati ẹniti iṣe olododo, ki o ma ṣe olododo nṣo, ati ẹniti iṣe mimọ, ki o ma ṣe mimọ nṣo. Si kiyesi, Emi mbọ nisisiyi, ere mi si mbẹ pẹlu mi lati fifun olukuluku enia gẹge bi iṣẹ rẹ yio ti ri. Ifihan xxii. 11. 12.

Oriki yi, ati ọrọ Ọlọrun yi ṣe gẹ pẹlu owe Yoruba kan ti o ni "Ẹniti o gbin ebu ika, ori ọmọ rẹ ni yi o hu le, gbe odo ru mi, ki ngbe alapa ( briki nla banba ) ru ọmọ rẹ." Bi a ba ranti oriki yi nigba gbogbo, yi o ma ka wa lọwọ ko lati ṣe ibi, ati lati tẹra mọ re 'ṣe, nitoripe ọkan ki gbe. Ire lo nṣe ? ko ni gbe, eyiti a ba ṣe lao gba ere rẹ, on lao ko ni esu. Ọkan ki gbe, eyiti iwọ na nṣe yẹn ko ni gbe o. O ko gbọ bi o.

AJALOKERU.

# EKO AKETE.

Eko, Saturday December, 9, 1922.

## JẸ KI ẸNITI O RO PE ON DURO ṢỌRA, KI O MA BA A ṢUBU.

Kẹkẹ p' ohun m' awoko lẹnu nigbati ìhin kan ni nibi pe Adajọ Sir F. A. Vender Meulen, ti o lọ lati ibi fun ẹjọ didá ni Abẹokuta, ju ọgbẹni John Olawunmi George, Onidajọ Kôtu ọmọ-ibilẹ ti Ake s' ẹwọn ọdun marùn, nigbati o dá a lẹbi ẹ̀ṣẹ ti a fi sun u, pe o jẹ "riba" nipo iṣẹ rẹ̀ ni akoko kan. Dajudaju iru ohun ti o ṣẹlẹ yi ko le ṣe ki o ma mu olukuluku enia dudu, pẹlupẹlu awa Yoruba apa ibi warìri, ki o si dojutì ni fun iyọṣuti si awọn ẹlomiran ti o le mu wọn wipe "ko si bi a ti mã ṣe Ifa ti ko ni hu 'wa ekurọ," eyini ni pe pupọ ninu wa ti o wa ni ipo pataki kĩ ṣai bu ẹ̀tẹ́ lu awa to ku ti iwa-aiṣododo irufẹ awọn bẹ ba di hihan, tobẹ ti o fi jẹ pe oluwa rẹ̀ tun di ẹniti a nrámu lati ba ro ẹjọ ẹṣẹ na. Ṣiṣubu arakunrin wa yi ya ni lẹnu lọpọlọpọ, nigbati a bá ṣakiyesi iye ọdun ti o ti wà lẹnu iṣẹ Adajọ na, ti o nlọ si bi ọdun mọkandi-logun.

Ti a ba ni ipo wo li o ni ọla, ẹ̀yẹ́ ati ibọwọ-fun ti o si tun lewu ju ipo Onidajọ lọ, nitori idanwo ti o wà ninu rẹ̀, ti o si yẹ ki ẹniti a fi sinu rẹ̀ bẹ mã yera fun lọpọlọpọ ati nigbagbogbo: ipo Adajọ ni, Irufẹ itiju ti ẹ̀ṣẹ ọgbẹni yi muwa ko le ṣe ko má jẹ idina fun igbẹkẹle ti a ti nni si awọn ẹlomiran ti o wa ni ipo giga bi iru eyi. A mọ pe ẹru kan li o nmu ni bu igba ẹru: sibẹsibẹ, a dupẹ pe nkan ko bajẹ tobẹ ki a ma fi ri pupọ ninu awọn ara wa miran ti o wa ni ipo nla ninu Iṣẹ-ọba tabi Iṣẹ ilu, ti nwọn ko fi aye silẹ fun ẹṣẹ-idojutini kan lati lẹ mọ wọn. Adura wa ni pe ki irufẹ awọn bayi ma ṣai mã pọ siwaju ati siwaju, nitoripe awọn bẹ̀ li o njẹ́ iṣiri ati igberaga awa to ku.

Ẹ jẹ́ ki a fi ti arakunrin wa yi k' ọgbọn pe ipòkipò ti a ba pè wa si, ki a sa pa lọsan-loru, pẹlu adura ati ãwẹ̀ ki a mase bajẹ ninu rẹ̀.

Ẹwẹ, a tanma pe ohun miran ti o nkoba awọn ti o wà ni ipò giga bi irufẹ eyi ni igbagbera; eyi si ti ṣe ọgọ̀rọ̀ enia lọṣẹ; ìwa "Awa li a wà nibẹ" "Tani nsọ to nsọ?" ko pẹ já ni tilẹ̀, ayaṣebi oluwa rẹ̀ ba "kamba" ara rẹ̀, ti ko si fi àye fun erokero lati ba a ni iṣe jẹ.

Ọ̀tọ̀tọ ọlọgbọn kan—Solomon—li o so pe "Orukọ rere sàn ju ọpọlọpọ ọrọ̀ lọ." Yio si jẹ́ ohun ti o dara, ti t' olori t' elesi wa bá nfi eyi sọkan nigbakũgbà, nitori nipa bẹ̀ ni a le fi ni ireti ati ṣe gudugudu-meje fun ara wa, fun Ọba wa, ati pãpã fun ilọsiwaju iran wa.

A kẹdùn ohun ti o ṣẹlẹ yi, a si mọ pe yio jẹ adura gbogbo wa pe ki a má tun ri iṣọ̀nú bayi mọ.

A ko sa le mã pe ni li olè, ki a mã gbé ọmọ-ẹran jó!!!

---

## ORIN FUN AWỌN AGAN TI NTỌRỌ ỌMỌ LỌDỌ ỌLỌRUN.

Ọmọ rọjo wa lọrun,
Ka le ri un gbe pọn ka ri un rọ,
K'ọmọ kekere jojolo j'alejo ko wa s'aiye
Ka ri un ṣere ẹ wa.
Agan nw' ọmọ pọn ọmọ wa aiye,
Ọmọ bo de ko mà dẹhin tori iyi 'wọ laṣọ wa
Ọmọ to dara wa ba mi.
Ọmọ ko ṣọwon lọdọ Ọlọrun
Agan ko ke p' Ọlọrun ogo f'ọmọ.

## ORIN FUN AWỌN ẸNITI AṢẸṢẸ FI SINU ISIN IGBAGBỌ.

Aṣiri isin wa ni
Ẹni to ba gbagbọ iyẹn a yege.
Awamaridi ọrọ ọgbọn mi' o to la de
Ka fi we ti Ọba to da mi
Mo gboju mi soke ni ṣiṣọpẹ
Temi pẹlu iwariri mo ki wọ ododo Ọba;
Jẹ ki anu Rẹ gbe ile mi
Emi ma gbagbọ tọkan-tọkan mi
Bibeli mimọ ohun ti mo ka ninu rẹ o.

Makanju.

## Oran Ilu Nigeria No. 4.

---

Aṣaro ti ogbẹni HERBERT MACAULAY oloye C.E., ṣe lori ọrọ ti DR. JOHN RANDLE oloye M.B.,C.M. sọ ni Ilu oyinbo ti a tẹ si Iwe-irohin ti a npe ni West Africa ti ọjọ keji oṣu September, 1922.

Koi ju oṣu mejila lọ nisisiyi ti DR. JOHN RANDLE tun ko awọn ikọ mẹtala kan lọ si ọdọ GOMINA kekere COLONEL MOOREHOUSE, nwọn ni ko ṣa wa Eleko lọ dandan ati awọn Ijoye rẹ, okanṣoṣo ti ipo rẹ kere ju ninu awọn oloye ni nwọn ko darukọ pe ki Ijọba wa lọ.

Ki ọwọ le tẹ ohun ti nwọn nfẹ (Ogbẹni J. HENRYSON DOHERTY, ati DR. MAGNUS L. MACAULAY, nwọn ma tu 'tọ s'oke, nwọn ma f'oju gba o, pe kiula awọn ko le lọwọ ninu iru nkan bayi) nwọn sọ fun Ijọba pe ara Eko ati ilu oke diẹ si wọn, atı pe ara Eko lo si nkọ wọn ni ilu oke, nwọn si nmura ati dide l'Eko ati kakiri gbogbo ilu lati pa gbogbo oyinbo, ohun ti Ijọba si le ṣe lati pana irufẹ ọtẹ nla yi ni, ki a wa Eleko ọmọ Alade lọ kuro ni ilu, on ati awọn Ijoye onifila funfun, ti nwọn f'ọwọ si iwe pe awon f'ori fun Ọba ilu Gẹsi, awọn si wa labẹ aṣẹ Eleko gẹgẹ bi alaṣẹ wọn ati olori ile Dosunmu.

Awọn ọtọkulu wọnyi gbagbe pe "olukuluku irọ ti a npa, ni Maleka nsunkun fun."

Alaironu ọmọ-ọdọ kan ninu awọn Ijọ "ṣika gbọn" yi tilẹ gba a l' amoran pe a ba tilẹ fi Ogbẹni HERBERT MACAULAY kun awọn ti a o wa lọ yi ko le ṣe gbukẹ diẹ.

Bi o tilẹ jẹ pe oga alasọdun ninu awọn ẹgbẹ yi gbidanwo ati sọ pe ọrọ yi ko ri bẹ, nipa ṣiṣapejuwe pe Ọgbẹni HERBERT MACAULAY ko to ẹniti awọn ti e jẹ jẹ ki oruko rẹ kọja lẹnu wọn ki o ma ba ba ete wọn jẹ, sibẹsibẹ, sisẹ ọrọ yi ko mọ 'yan lori.

Awọn aṣaju ? enia dudu wọnyi ni lati mọ pe :—

O dara pupọ lati ku fun otitọ ju ki a purọ nitori ati wa laye.

GOMINA kekere ṣ'ọyaya si wọn, o tẹti lelẹ gbọ gbogbo ohun ti nwọn wi pẹlu suru nlanla, o si sọ pe on o mu ọrọ na lọ siwaju Ijọba.

Awon ilu ke si Ogbẹni J. EGERTON SHYNGLE, agbẹjọro olokiki, ati aṣaju awọn ara Eko pataki, pe kiyakiya ko ma jẹ ko tutu, ki o lọ sọ fun GOMINA kekere pe awọn papa na fẹ ri i; iyẹn ke, ti o ti je omoluwabi lati ilu rẹ wa, ki o to to wakati merinle-logun ti ilu ti kan si i, o ni ki nwọn ma bọ, ki on le gbọ apakeji.

Adele GOMINA agba, ọlọla DONALD C. CAMERON C.M.G., ẹniti a ko ọran yi lọ siwaju rẹ, nigbati o f' oju wo gbogbo bi oran na ti ri, o ri pe ero buruku ni nwọn gba, ko tilẹ pẹrẹkẹ lu ọrọ na mọ "o dabaru ọgbọn arekereke wọn" o t' idi alaṣeju b' omi 'gbona.

Ninu ọna ainitiju bayi, ni awọn ojo yi lọ ba Ijọba *Nigeria* pẹlu ọrọ aponle lati fi ọwọ si ọtẹ eyi ti nwọn dimo Eleko ọmọ alade, bi o tilẹ jẹ pe awọn alabinuku ojo wọnyi ti o di tẹmbẹlẹkun na ko ju ṣaṣara lọ, ti oga wọn si sọ nisisiyi nigbangba pe "ede aiyede haun lo wa larin Eleko ati diẹ ninu wa." Nigbamiran ijẹwọ dara fun ọkan.

Ko le ye DR. JOHN RANDLE eredi rẹ ti Sir HUGH CLIFFORD ṣe yi ero rẹ pada, lẹhin igba ti o ti ro o daradara, ti ko si fi gba amọran eyiti awọn "ti o to oju abẹ sọ niko" fun u pe didaduro ti BOYLE GOMINA kekere da Eleko ọmọ alade duro ki o maṣe tu u, ko tẹ ẹ l' ọrun ti o jẹ ki awọn ẹgbẹgbẹrun enia wa ri, ti nwọn si sọ fun u pe ko tu eyiti BOYLE GOMINA kekere ṣe, nitoripe gẹgẹ bi DR. JOHN RANDLE ti wi" nwọn ko ladi rẹ kini ṣe ti nwọn wa tako eyiti awọn aṣaju enia dudu mẹtala ni wa sọ awọn ẹniti ede aiyede haun wa larin wọn ati Eleko.

Laika eredi dada ni eyiti GOMINA agba sọ ninu ẹsẹ ikini ati ikeji ti afikun keji ni ori ogbonlerugba ole kan iwe ti o ka ninu ajọ igbimọ *Nigeria* ni ijọ kokandilogbon oṣu *December* 1920 si, pẹlu ọpọlọpọ ibinu ati irunu to tilẹ fẹrẹ ma'le sọrọ, Dr. JOHN RANDLE sọ pe "Sir HUGH CLIFFORD gbọ ẹbẹ wọn, o ba Eleko wi, o si fi si ipo rẹ pada."

Dr. JOHN RANDLE ro pe ẹṣẹ nlanla ni fun eyikeyi ninu Gomina Eko, ki o ronu fun 'ra rẹ, ki o si ṣe ẹtọ lailai gba ti on ti awọn ọmọ ẹgbẹ "t' ọlọmọ kan l' oṣoro" *Nigeria* miran, awọn aṣaju enia dudu ni *Nigeria* ati kakiri ibi gbogbo.

Ṣugbọn, wọn wa ni bi a ba ṣubu a m' ẹru di, nwọn le ṣonṣo, k' a wa nlo oniruru ọgbọn ẹwẹ lati ri Eleko mu, titi aye fi wa de fun wọn nigbati a pe Eleko ki o wa yọ 'ra rẹ kuro ninu ọrọ kan ti a sọ pe HERBERT MACAULAY sọ ni *London*, ẹniti o jẹ agberari *Nigeria* ninu orọ ilu, ti o jẹ akọwe ati ogbufọ, ti o si ngbe ọpa oye niwaju oloye Oluwa ni *London*.

Nigbana ni awọn aṣelu ọranyinranyin wọnyi ti o ni "ede aiyede haun larin wọn ati Eleko, wa ri aye ti nwọn ti nwa lat' ọdun m' ọdun, lai bere bi yio ti pari; Dr. JOHN RANDLE wa fo s' oke fun ayọ, o kigbe rara o ni :—

"Sir HUGH CLIFFORD pe Eleko pe ki o yọ 'ra rẹ kuro ninu nkan ti HERBERT MACAULAY nsọ. Eleko kọ.

Sir HUGH CLIFFORD bẹ ni 'ba ba, o bẹ n' ikọkọ, sibẹsibẹ Eleko tiri. Nibe ni Sir HUGH CLIFFOR wa ro pe iṣẹ on ni lati rọ l' oye."

Dajudaju inu Dr JOHN RANDLE ati awọn ọmọ lẹhin rẹ nikan lo dun nigbati Ijọba ni awọn yọwọ kuro niti Eleko, ti nwọn si da owo rẹ duro.

Ṣugbọn Dr JOHN RANDLE nigbati o ngbidanwo ati mu ẹsẹ pataki jade ninu eyiti Eleko ṣe yi, ti inu rẹ si dun tan, o ni " nigbati a gbe Ọpa yi de *England* Ogbẹni HEBERT MACAULAY ngbe e ilu Oyinbo nipa ti ẹtọ ati iwa itiju ti o wa rinu iwe adehun.

Akoko yi gan ni awọn Jamani nsọ pe arekereke ni orilẹ ede Gẹsi fi nni ilu amọna wọn"

Laifagun lọ titi, ede alaimore kan ko ju eyi lọ

Lọni Dr JOHN RANDLE nmi fẹ ninu ile kan na ebute *Marina* l' Eko, aṣoju Ijọba Jamani ti a npe ni Ọgbẹni *Edoward Schmidt*, lo san Ẹdẹgberin Ponwun o din kan fun ibẹ nigbati Dr JOHN RANDLE si wa ni oniṣegun a Ṣẹṣẹ won Ologbo lo njiya. CONSUL SMICHDT ara ilu Jamani ni. Nigbati Dr JOHN RANDLE si kọ iṣẹ Ijọba Eko silẹ, tabi ti Ijọba Eko kọ O silẹ gẹgẹ bi nwon ti ṣe ni Ọdun 1893 ( e lọ wo afikun ) awọn ti o ran lọwọ pupọ ju ati fun igba pipẹ, pẹlu owo wọn ni awọn Oniṣowo ara ilu Jamani ti ngbe Eko nigbana.

" Iwa aimore jẹ ẹṣẹ ti o ti ni l'oju tobẹ ti a ko le ri ẹnikan tio ma gba pe loto alaimore ni on."

Mo wa ni *London* pẹlu Oloye Oluwa lati *June 1920* titi di *August 1921*, gẹgẹ bi Dr JOHN RANDLE si ti sọ, o jẹ pe mo nwasu ọtẹ ati Tẹmbẹlẹkun ni arin ilu Oyinbo ni ọdun Keji ti ogun pari. Fifori fun Ijọba ti Dr JOHN RANDLE.

(*a*) Sugbon ninu ipade ti a ṣe ni gbangba ita Tinubu ni ojọ *Friday* ijọ kẹrin Oṣu *August 1916*, ni ọdun keji ti Ogun ; nla ni Ṣẹṣẹ bẹrẹ, *Governor* agba ti Nigeria wa lori aga ; nigbati Dr JOHN RANDLE fẹ ki a gba ipinnu pe a wa t'ọwọ t'ẹsẹ ninu Ogun na eyiti ilu Gẹsi ati awọn Ọrẹ rẹ nya, O Sọ ọrọ nwọnyi pe :-

" Ako le di 'ra wa ni ibo ikoko bi a ko ba sọ pe ninu ilu yi papa, a ṣakiyesi pe Ijọba isisiyi ko tẹ awọn enia l'ọrun. Awọn enia ri pe, Ijọba isisiyi ko wa ire wọn "

( Wo ori keji, ẹsẹ kẹrin ọrọ ti Dr RANDLE ti C. M. S. *Bookshop* ti Eko tẹ )

Nitoto iyatọ ti o wa nihin ni pe :—Ni Oṣu *August 1916*, Ogun nla ni ṣi wa aikorira ẹni si wa, ajẹnbẹni agabagebe yi ko gbe Ọpa Eleko kiri nigbangba nitorin pe Eleko papa wa lori atiba, On ati Gomina agba, awọn Jamani Ọrẹ rẹ si wa lẹnu ija ni ilẹ *France* ati *Belgium*, wọn ko si r'aye ati fi " awọn ilu Gẹsi Sun pe iwa agabagebe ni nwọn fi ni ilu amọna wọn "

(*b*) Ni arin Ogun nla ni, ko i ti ni iye ọdun, Dr. JOHN RANDLE ko awọn ikọ ile Gomina nigbati adele Gomina F SETON JAMES C. M. G fi won sun pe ifẹ ete ni nwọn ni si Ijọba.

Pẹlu ibinu ni adele Gomina fi dide lori aga, bi o si ti ju wọn silẹ ti o nlọ lainani wọn mọ, ni Dr JOHN RANDLE dupẹ lọwọ adele Gomina pe On dupẹ ti o jẹ ki awọn wa ri on.

(*c*) Ninu Oṣu *July* ati *August 1915*, ni arin Ogun nla ti o kọja, Dr. JOHN RANDLE ati awọn isọngbe rẹ ti o nfi, " ibanujẹ, Osi ati ainitẹlọrun awọn ara ilu rẹ han " ( gẹgẹ bi nwọn ti so ninu iwe won kan ti nwon fi ṣowọ si ilu Oyinbo ni ijọ kejdilogun Oṣu *Novmber 1915* ) nwọn fi waya meji kan ṣowọ tara si Akọwe agba ti ilu Oyinbo ni ijọ kọkandilogun Oṣu *July 1915* ati ijo kẹfa Oṣu *August 1915*. Akọwe agba ninu iwe rẹ ti ijọ Ogbọn Oṣu *August 1915* ti o kọ ṣowọ si Gomina agba ti Nigeria sọ ọrọ ibawi bayi pe :—

" Nipa fifi waya ṣọwọ si mi tara bayi, awọn ti o hu iwa yi ṣa ofin ti ilu amọna ti, eyiti o wa ni ẹsẹ 211, 212 ati 213. Mo si fẹ ki o fi ofin yi han won, nitori ni ijọ miran, ti nwọn o ba tun tẹ waya, ki nwon ṣe e lọna ẹtọ nipa fifi ranṣẹ lati ọdọ Balẹ ilu ati Gomina agba.

5. Mo ṣakiyesi pe nwọn sọ pe nwọn f'ori fun Ijọba ninu waya wọn ti ijọ kẹfa oṣu *August*, ngo si fi eyi siwaju Ọba.

Mo gbagbọ pe wiwa ti ọrọ yi wa ninu waya na fihan pe awọn ti o jẹ aṣaju ninu rogbodiyan yi wa ke abamọ ọrọ otẹ eyiti o wa ninu waya won iṣiwaju laisi anfani yio ye wọn pe, iṣẹ awọn eniti o fi ori fun Ijọba ni lati kọko tẹriba fun awọn ofin ilu rẹ." Ki Dr. JOHN RANDLE kọkọ yọ iti kuro ki o le r'aye fi ko to nkan han.

(*Koi ti pari.*)

---

## "FALANỌ GBỌ TIRẸ, TARA ẸNI LA'NGBỌ."

Ifesi si ọrọ Aromirẹ onilẹ ; " Ọlọtọ ni ti on otọ" ninu *African Messenger* ti ijọ kẹtalelogun oṣu *November*, 1922 ti nwọn sọ labẹ Yoruba *Column* pe "Ọlọto ni baba gbogbo Idẹjọ, on ni Ọba papa" mo fẹ ki awọn ti o kọ iwe yi ki o dahun awọn ibere wọnyi bi ogun wọn ba da won loju :—(*1*) Kini nwọn mọ nipa eto awọn Idẹjọ ? (*2*) Bawo ni Ọlọtọ ti ṣe jẹ baba gbogbo Idẹjọ ati Ọba ? (*3*) Awọn wo ni Ọlọtọ jẹ Ọba fun ri ? (*4*) Tani si nfi Ọlọtọ jẹ Ọba na ? O yẹ ki gbogbo ilu mo pe iru awọn enia to nsọ itan ti nwọn ko mọ, lo nba ilu jẹ ti wọn si nda rukerudo silẹ larin ilu nigbati Ọlọtọ joko jẹ, ti Aromirẹ joko jẹ ; kini ṣe ti nwọn fẹ fi wọn gbun ara wọn ? ọrọ ti enia ba mọdi rẹ lo yẹ ko sọ, enia ki i sọrọ ti oju rẹ ko to.

( *Koi pari* )

## CLIMAX

World's wonder hair beautifier for men only.

Will straighten the most stubborn, coarse, or kinky hair in five minutes, make hair lustre and silky, without the least bit grease, absolutely harmless.

Sophia's cream brown Pomade known as a national hair remedy which feeds, nourishes and beautifies the hair, will eradicate dandruff, grow your hair long, lustrous, soft and fluffy for women and men; Also assorted kinds of pomade and toilet soap in stock.

Dipo Tunde, & Co.,
P. O. Box 335,
37, Ajiṣomo Street,
Lagos, Nigeria.

---

## The Brotherhood Christian Church.

**Revival Meetings and Harvest Thanks-giving Service**

**December 17 to December 24, 1922**

7 P.M.

**ILUPESI HALL.**

*Addresses by*

Pastor A. Adedeji Isola, F.B.P.I.,
(*Fellow, British Psychological Institute*)
*Founder and Superintendent.*

*Note*

1. Special Hymn Sheets will be sold at 3d a copy at the Gate.
2. Silver Collection every evening to defray expenses.
3. ALL ARE CORDIALLY INVITED.

AMOS I. COLE,
*Parish Secretary.*

---

## Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER.

**OYINBO GERMAN ONIṢOWO NI HAMBURG**

fẹ ka sọ fun nyin pe ẹ le wa wo orişirişi irepe ọja pẹlu iwe-ọja on ni.

Ile-Owo rẹ *No. 7,* Ita Labinjọ,
leti Ita William l' Eko.

Yi o tete bojuto iwe ti ẹ ba kọ si i, ti ẹ ba si fi sinu apoti iwe rẹ No. 459, ni ile-ipinwe t'Eko, ati iwe-ti ọja ti enia ba fẹ ranşẹ lọdọ rẹ. O yẹ ki awọn onibara rẹ tete wa ranşẹ ọja wọn fun akoko oşu Awẹ ki o ba le tete de: oniruru oja lo le ranşẹ fun ẹnikẹni, o si ni ọgọrọ ọja lorişirişi.

Ẹ wa wo o !!!

---

## The very Books you need !!

| | |
|---|---|
| General knowledge Test papers | 1/- |
| Key to above | 2/- |
| Ready's precis and precis writing with key | 3/6 |
| Forks Essays and how to write them | 2/9 |
| Dixon's English Idioms ,, ,, | 2/6 |
| Nancanow's "Notes in Hygiene" | 1/6 |

The "ORA" Book Syndicate,
(P.O. Box 278)
*33, Obun Eko Street, Lagos.*

---

## BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni "MAGARINE"

Ọlọja'Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Onişowo,

**STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.**

Ni Ibode lailai (Custom Street) L'Eko

Şile kan pere ni panu kọkan; o şe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to lyẹpẹ, şugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

---

Are you impotent suffering from sexual nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neuiasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sore and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that trouble-some Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6 These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

Vidal R. Cole

"Ajenifọja" Store
P. O. Box 201; 109 Broad Street Lagos.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. ( Morning )

Masses Isin Arọ,

6.30—7.30 8.30—9.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

( Evening.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30

St. Michael's ( Lafiaji.)

Morning. 7 a.m —8 a.m. 8.30 a.m,—9.30 a.m.
Evenning. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. do. |
| 9 a.m.—St. Paul's ( Breadfruit ) | Rev. James Pearse |
| 6.30 p.m. | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9. a.m.—St. John's (Arọloya) | Rev. S. M. Abiọdun |
| 6.30 p.m. | |
| 4 p.m. ( Confirmation Service ) | Rt. Rev. Bishop Oluwọle |
| 9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity ( Ebute Ero ) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m.—St. David's (Jordan). | Rev. J. A. Leigh |

WESLEYAN

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. J. C. Cole |
| 7 p.m. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | Bro. S. A. Stowe |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. D. A. Beckley |
| 7 p.m. | do do |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Bro. Adebiyi Tepowa |
| 7 p.m. | Bro. D. A. Ogunbiyi |

AFRICAN (COMMUNION)

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | Rev. Supt. G. A. Oke |
| 9 a.m.—Erelu | Bro. T. D. Shaw |
| 4 p.m. | Bro. J. H. Lawson |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. E. A. Akiọla |
| 6.30 p.m. | Bro. J. B. Coker |
| 10.30 a.m.-African Methodist | Bro. J. K. Coker |
| 4.30 p.m. | Rev. I. E. Oyekunle |
| 9 a.m.—Ararọmi Church | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | Bro. M. D. Adegboye |

EBENEZER

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. S. M. Phillips |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

AHMADIA.

5.30 p.m.—Open Air Service Prof. A. R. Nayyar ( Luther Street.)

COLONIAL CHURCH (ODAN)

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

Owo Iranlowo ti a ṣi ri gba ni wonyi.

| | | £ | s | d. |
|---|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | | 10 | 4 | 3 |
| Ọgbẹni D. O. Thomas | ... | 0 | 5 | 0 |
| " Bakare King | ... | 0 | 5 | 0 |
| " A. W. Olukolu | .. | 0 | 2 | 6 |
| Aropọ | | £10 | 16 | 9 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ma jẹ ko rẹ nyin,

A o ma jihin yi lọsọsẹ,—[Ed.—E. A.]

Don't wait the moment of need!

Provide for the time of Emergency!!

The Nigeria Labour Corporation is established as a "City of Refuge" for all classes of work-people, and is open to all to come and join.

It is the only independent organization protecting the interest of all its members in points of business in all parts of Nigeria.

If you are unjustly treated by your employers, the Corporation will fight freely for you to secure your Right.

If you are out of employment, the Corporation will assist you to obtain employment.

Make no hesitation, insure your business interest by becoming a member.

THE NIGERIA LABOUR CORPORATION.

Write for terms (enclose stamp for reply) to 51 Palm Church Street, Lagos Nigeria

Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o si "Sabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo.

Ogun rẹ jire.

St. STEPHEN'S (EPETEDO.)
9. a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

BROTHERHOOD.
7.30 a.m.—Ilupesi Bro. J. A. Adesanya
7 p.m. " Prof. Deniga

"O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta oriṣiriṣi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street.*) EKO.

Awọn Oyinbo oniṣowo yi nranṣẹ MAṢINI-ARANṢỌ ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAṢINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe oriṣiriṣi Ilẹkẹ alarabara. Nwọn si nranṣẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipọn, ati ọja Abọmafọ ati oriṣiriṣi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi ṣi nigbakugba fi enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AṢIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta oriṣiriṣi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street.*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kojusi Kọtu, l' Eko.

ỌGBẸNI DURO THOMAS.
ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni oriṣiriṣi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn oniṣowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

ILE EGBOGI IṢẸ OLODUMARE.

A ṣi ile Egbogi kan ti a npe ni Iṣẹ Olodumare si ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri oriṣiriṣi iwosan fun oniruru aisan, Ibaṣe fun Orififọ, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinniṣa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọṣẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tilẹ gbọ oruko rẹ ndan?
Iṣẹ Olodumare !!!
JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

## F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo oniṣowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ loriṣirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'. ko.

---

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

AWON ẸGBẸ OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

## E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn oniṣowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranṣẹ ọja fun enikẹni to ba fẹ' ibaṣe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria.*

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French.*

Oruko adugbo awọn Oyinbo oniṣowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA.!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS. WRITER AND LECTURER.